307 4/77
IBADAN.

WEEKS 40&41
Kongi WK 40
22 31 43
Wk 41
22 23 24
Asiko BK WK 40
27 28 29 48
Wk 41
3 5 9 16
Ross Wk 41
1 & 20
WK 41
4&19

# Imọlẹ Owurọ

EṢIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 40
NAP 16 29 42
Perm 4 8 16 29 42
My Address ?
Not nessesary,
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
**1 23 42**

Independent Paper Vol. XV NO 795 SATURDAY APRIL 30 — FRIDAY MAY 6, 1977 10K. (KOBO MEWA)

# OKUNRIN KAN BE ỌLỌPA LORI SỌNU

ỌKUNRIN kan ti bẹ Ọlọpa kan l'ori sọnu, o si fi ada ba aiye awọn Ọtẹlẹmuyẹ mẹta miran jẹ.

Ni ipari ọsẹ ti o kọja yi ni iṣẹlẹ buburu na ṣẹlẹ ni ileto Izzi lẹba Abakaliki ni Ipinlẹ Anambra.

Irohin lati iha ibẹ fi ye wa pe l'ojiji ni ọkunrin na yọ si awọn Ọlọpa na nibi ti nwọn ti nṣe iwadi kan lọwọ ti o si da ada bo wọn.

Orukọ Ọlọpa ti iku pa lẹsẹkẹsẹ ninu ikọlu na ni Nicholas Ike ti o jẹ Dẹrẹba ti o wa mọto awọn Ọtẹlẹmuyẹ na lọ sibẹ.

Irohin sọ pe, ohun ti o padi ọrọ na ni pe, ninu oṣu keji ọdun yi ni ọkunrin kan fi ada ṣa enia meji pa, ṣugbọn ọkunrin na na papa bora lẹsẹkẹsẹ, ẹnikẹni ko si ri i mu. Iṣẹlẹ na ni a gbọ pe awọn Ọtẹlẹ—

(Woju Ewe Kẹjọ)

## LAYIGBADE TUN GBE DE O!

EYI ni lati kede fun gbogbo aiye pe, rẹkọọdu titun ti olokiki alare sakara asiko nni, Saka Ọlayigbade ati Ẹgbẹ Alare Sakara rẹ ṣẹṣẹ ṣe, ti ẹ ti nbeere rẹ lati bi ọjọ mẹta wa, ti jade fun tita bayi.

Awo rẹ titun yi gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ Saka Layigbade ni alare atata, kọyọyọ, o miringindin o si le gongo Nonba awo na ni OLPS 0121.

OJU KINNI

Ara awọn ohun ti Saka Ọlayigbade kọrin le l'oju kinni awo na ni:

1. Oloogbe Alhaji Latifu Owokoniran
2. Raimi Ọladipupọ
3. Mọṣudi Anifowoṣe
4. Orente

OJU KEJI

1. Pẹki mo k'ore
2. Ko s'oriṣa bi iya
3. Ejirẹ Eyilaki
4. Ọyadolu

OGUNMỌLA ATI AGBỌMỌJO

Bakanna ni awo ti Alhaji Fatai Ogunmọla ati Alhaji Amuda Agbọmọjo pẹlu are dundun ati Ṣẹkẹrẹ ti nọnba rẹ jẹ OLPS 0110 na ti wa fun tita bayi.


SAKA ỌLAYIGBADE

Koṣeemani ni awọn awo mejeeji yi jẹ. Bi nwọn ti dara fun arikọgbọn ni nwon dara fun ariya ati faaji.

DAUDA EPO AKARA

*Ẹ f'oju sọna fun awo Alhaji Dauda Epo—Akara ti a o bẹrẹ si i ta laipẹ yi.

Beere awọn awo meji ti a sọ ṣaaju ni gbogbo ile itaja rẹkọọdu ni adugbo rẹ tabi l'ọdọ Olupinja:

ADETUNJI RECORD STORES,
2, Ibomo Street
Ita Agarawu, Lagos.
Tele. 26813.

* Sw3/51 Adetunji House, Popoyemọja, Ibadan.
* Sw6/431 Old Armel's Rd Ogunpa, Ibadan.


ỌBA AJAGUNGBADE KẸTA
Ṣọhun Ilu Ogbomọṣọ

## Ajagungbade be Alaafin wo

NI ipari ọsẹ ti o kọja ni Ṣọhun Ogbomọṣọ, Alaiyeluwa Ọladunni Ajagungbade Kẹta bẹ Alaafin Ọyọ, Alaiyeluwa Ọlayiwọla Adeyẹmi Kẹta wo ni aafin rẹ nilu Ọyọ.

Irohin ti a gbọ fi ye wa pe, tẹrintẹyẹ ni awọn Ọba mejeeji fi pade ara wọn ti nwọn si takurọsọ.

Ninu ọrọ rẹ, Alaafin Ọyọ, Alaiyeluwa Ọlayiwọla Adeyẹmi Kẹta sọ pe o tọ o si yẹ ki awọn Ọba maa bẹ ara wọn wo nitori ki irẹpọ le wa laarin awọn enia wọn si ara wọn.

Ọba na kan saara si Ijọba Ologun ti o nbẹ l'ode bayi fun ipo ọla ti o to awọn Ọba ilẹ Naijiria si.

## Oyerinde jade laiye

NWỌN ti kede iku ọkan pataki ninu ọmọwe akọkọ nilu Ogbomọṣọ, Ọjọgbọn N. D. Oyerinde ti awọn enia maa npe ni "Kofẹsọ".

L'ọsẹ t'o koja ni o jẹ ipe Ọlọrun nilu na lẹhin ti o ti lo aadọfa ọdun l'aiye (110years) gẹgẹ bi a ti gbọ.

Oloogbe na ni akẹkọ akọkọ ti nwọn kọ gba wọ ile ẹkọ giga Baptist Cellege nigba idasilẹ ile ẹkọ na ki nwọn to ko ile iwe na lọ silu Iwo.

Ọjọgbọn Oyerinde jẹ

(Woju Ewe Kẹjọ)

# ATIORO ỌMỌ ATIALA

## Oore t'o dara (7)

ONI l'a o pari ọrọ yi
T'a o pari Nasia;
L'ori ohun gbogbo
T'o jẹmọ oore şişe
Nitori a ti sọrọ
A ti şalaye jinna.
A pa obi,
A yọ abidun,
A yọ doomọ
A sọ ọ yanju gbogbo,
A şalaye to
A si tun şapẹrẹ ọrọ.
Bi ẹ ko ba gbagbe:
A sọ iru oore
Ti a le şe
T'o le ba
Ọlọrun Ọba nile;
A sọ eyi
Ti ko tọ rara
Niwaju Olodumare.
A sọ eyi t'o lu mọ ẹşẹ.
A sọ eyi
T'ọmọ araiye işe
Ti ko l'abọ rara,
A si tẹnumọ
Eyi t'aiye nşe




Ti ko tọ rara
Şugbọn ti
Ọmọ aiye nro pe,
Oore t'o dara ni
Awọn nşe kiri,
A si sọ idi ọrọ
Ti gbogbo rẹ fi ri bẹẹ.
Bi ẹ ba ranti
A sọ f'onikaluku
Lati mura si
Oore şişe
Bi ẹ ti nbẹ l'aiye;
Ẹ maa huwa aanu,
Ẹ maa şe 'ranwọ
F'ọmọ ẹnikeji;
Ki ẹ maa ranti
Pe, oore Ọlọrun ni
Gbogbo wa njẹ,
Ko s'eeyan
T'o wa l'aiye
Ti nda ọla ara re lo
Ninu awọn ọmọ eniyan.
Bi o ba nsọ pe,
Ẹnikẹni ko ran ọ lọwọ.
"Iwọ l'o da tobi,
Iwọ l'o da tobi"
Ninu aiye;
Bi o sọ pe,
O ko r'eeyan ran ọ lọwọ
Ti o nsọ pe
Atapata dide l'o jẹ
Ninu aiye gbogbo
Bi o ba tori eyi
Ti o sọ pe,
O ko ni i şe 'rawọ
O ko nii ş'oore f'ẹnikan:
Yiye ni ko ye ọ o
Ede ni ko ye ọ
Nitoripe:
Didide t'o dide
Kii ş'agbara rẹ,
Ọlọrun Ọba l'o şe e
Bi ko tilẹ lo ẹbi rẹ
Lati ran ọ lọwọ.
Ranti pe,
Eniyan kan ni
Ọba Oluwa mi lo
O si pọndandan fun ọ
Lati şe 'ranwọ
F'ọmọ ẹnikeji
Ẹnyin enia
T'o maa ntẹnumọ ọrọ
Pe, ẹbi ko ran nyin lọwọ
Ti ẹ wa tori eyi
Ti ẹ kọ iha aidara si
Ẹbi nyin gbogbo
Aimọkan ni nşe nyin,
Ẹ ma huwa bẹẹ mọ
Nitori: o kuku ni
Ẹni t'Oluwa Ọba
Yio ran si ni
Lati şe ni l'oore
Gbogbo eniyan kọ ni
Ọba Edumare kadara
Pe, k'ẹbi rẹ gberoke.
A ti kilọ eyi ri,
Ẹ ma yọwọ iwa ibi,
Ẹ maa huwa t'o tọ
Ẹ si maa gbẹkẹle
Ọba Edumare.
Too, opin Nasia yi ree
Gbogbo ẹni
T'o ti ngbọ mi
Ninu aiye pata.
Taa l'ọrọ ko ye,
Taa l'o ti gbagbe ọrọ ?
Ẹni t'o ba gbagbe
Ẹ jẹ ko wẹhinwo
Ko lọ tun
Imọlẹ Owurọ ka
Nitori:
A ko mu Opo lu 'Ro,
A ko si şai şalaye
L'ori Nasia.
Oore dara
Şugbọn gbogbo
Oore kọ l'o dara.
Oore tọna
Gbogbo rẹ kọ lọ tọna,
Oore gba ẹsọ,
Oore gba ironu,
Oore gba arọra-şe,
Nitori:
Oore a maa fa iya,
Oore a maa fa iku,
Oore a maa fa
Ibinu Ọlọrun Ọba
T'o da gbogbo wa.
Abọ Nasia wa ree o
Gbogbo janmaa.
B'o ba wa d'ọsẹ t'o nbọ
Ng o sọrọ lori
Awọn onkawe
T'o fẹ mọ
Ẹni ti Atioro işe.

ỌLỌLA ATIORO



ALAIYELUWA ỌLADUNNI AJAGUNGBADE
Şọhun Ilu Ogbomọsọ

# Sohun nfe agbega ile iwosan

ŞỌHUN ti ilu Ogbomọsọ, Ọba Oyewumi Ajagungbade Kẹta ti rọ ijọba ipinlẹ Ọyọ lati sọ ile iwosan ti ijọba eyi ti o wa nilu Ogbomọsọ di eyiti o gbooro si i gẹgẹbi ti ilewosan ijọ Onitẹbọmi ti o wa nilu na.

Ọba Ajagungbade da a laba pe, nipa şişe bẹẹ, ki ijọba ri i pe oun pese awọn irin işẹ ati gbogbo awọn nkan elo ti o yẹ ki ile iwosan ti o to fi ọkan tẹ ni, ki awọn oşişẹ ti o ba si tun peye pọ si i nibẹ (specialist Doctors).

Şọhun pe awọn ipe yi nigbati Olootu fun eto ilera ni Ipinlẹ Ọyọ, Ọmọwe Adetoye Faniran lọ ki i ni aafin rẹ lakoko ibẹwo rẹ silu Ogbomọsọ laipe yi.

Amọşa o, Alaiyeluwa kansara si ijọba fun dida silẹ awọn igbimọ ti nmojuto eto ilera ni ẹku kọọkan lati maa mọ kini işoro awọn enia nipa eto ilera, ki nwọn si jabọ fun igbimọ nla (State Health Board/ Council). O ni nipa şişe bayi, ijọba ti fihan gẹgẹbi ifẹ ti o ni si awọn enia Ipinlẹ yi nipa ilera.

Ninu esi tirẹ si ipe na, Ajẹlẹ na fun ilera, Ọmọwe Faniran, dupẹ pupọ lọwọ Kabiyesi fun pipe akiyesi ijọba si bi o ti nfẹ ki ilewosan ilu rẹ ri. O jẹjẹ pe ijọba yio fi ọrọ na si ero.

Lara awọn enia patakipataki ti o tẹle e ni a ti ri awọn lọgalọga ile işẹ re, awọn Alaga Igbimọ ti nmoju to eto ilera ni ẹku Ọşun, Ogbomọsọ ati Ejigbo, Oloye L. Omitade, Oloye N. A Ad/bi pẹlu Alaga Agba, Dokita V. L. Lawọyin.

# Babalola jade l'aiye

NWỌN ti kede iku Oloogbe Mustapha Babalola ti o jẹ okan ninu omo idile oye Alapinni ilu Ọyo (Ọkan ninu Ijoye Ọyomesi ti işe Afobajẹ Ọyọ) ẹni ti o filẹbora bi aşo laipẹ yi ninu ile rẹ ni 102 Odunfa St. l'Eko.

Lẹsẹkẹse ti oloogbe Mustafa Babalọla ẹni ti o jẹ gbajumo Onişegun Ibilẹ nilu Eko ti fi aiye silẹ ni Ọmo rẹ gbe oku rẹ lo silu Ọyo nibi ti won ti lo sin in sinu ile rẹ ni adugbo Apinni lẹhin ti awọn Alufaa ti şe isin ikẹhin fun un gẹgẹ bi ilana ẹsin Islam nitori Musulumi Ododo ni Oloogbe na nigba rẹ.

Irohin fi ye wa pe nigbati o di ojo Ẹti ti işe ojo kejilelogun oşu kẹrin odun yi ni awon omo ati ẹbi Oloogbe na şe inawo ojo mẹjo oku nilu Ọyo nibiti ẹsẹ gbogbo awon enia jankahjankan lati ilu Eko, Ibadan, Lanlatẹ, Igbo-Ọra ati igberiko Ọyo pejupesẹ si.

Nwon fi jijẹ ati mimu tẹ awọn enia ojo na l'orun.

Awon omolooku ti won nawonara l'ojo na

(Woju Ewe Keje)

# ÌSỌRỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (53)

Adeyẹmọ Ojẹrinde
L'ỌSẸ t'o kọja, ọmọ Ejigbọjọ,
Mo sọrọ titi
Mo fun Naijiria n'imọran
O si ṣeleri pe
Iwọ yio sọ kun ọrọ mi
N'ijọ a ba pade l'ori ọrọ wa,
O ni, o o sọrọ kikun
B'o ba d'ipade t'o nbọ.
Ipade na l'o de yi o
Ewo l'o fẹ wi fun gbogbo wa ?.
Ayinde ! Tete kia
Jẹ k'a gbọ labare.
Lawuyi Ogunniran
O ṣehun l'iaye ọmọ Ajiṣegiri
Aisi aaye ni ko jẹ ki ng wi
Ninu ipade t'o gbẹhin.
Aṣe, ojo eniyan l'o jẹ
O ko n'igboya rara !
Ẹnu lasan l'o ni,
O ko l'aiya ọrọ ?
O mọ pe, o dara lati ṣ'otitọ,
Ṣugbọn o ko l'aiya
Lati duro ti otitọ rẹ ?
Iwọ le tori ibẹru eniyan
Ki o ṣẹ Ọba Olodumare!
O ko mọ pe,
Ọba Edumare fẹran olotitọ
Ko si ni i jẹ k'iya o le jẹ iru wọn;
O ko mọ pe,
Ọpọ eniyan nla t'ibanujẹ nba l'aiye,
Ati ọpọ eniyan pataki
Ti ibanujẹ nba ti ko le sọrọ
Bi a ba wadi ohun t'o fa sababi,
Afaimọ ko ma jẹ pe
Nibi ti nwọn ti doju ija kọ olootọ
Ni nwọn ti kagbako ibi.
Mo wa fẹ gba ọ n'imọran
Ọmọ Ajiṣegiri
Pe, ki o maa rọju niuu aiye
Maa sọ ododo nibigbogbo;
Ma tori ibẹru eniyan
Ki o ṣẹ Olodumare
Nitori pe, ko si eniyan
T'o le gba ẹda
N'ijọ Olodumare ba nbinu.
Ṣugbọn b'ẹda ba nbinu si ni l'aiye,
Ọba Olodumare l'O le gba ni
Aya fi bi ẹda ba jẹbi ẹṣẹ
L'Oluwa mi le ma gba a silẹ.
Maa ranti pe:
Bi a bẹru eniyan, a o ku;
Bi a ko bẹru eniyan a o ku;
Bi a ṣaalọ f'eniyan
Ko pe ko ma gbidanwo ibi si ni;
Bi a nwoju rere eniyan
K'o pe k'o ma ṣe 'luwarẹ n'ika;
Ki l'a ko kuku ṣ'ootọ si
K'a le ku bi olootọ ?
Bi a ba lọ nile aiye tan
K'aiye le rojọ ẹni n'ire;
K'o le d'iwalẹ asa tan
K'a jare niwaju Olodumare.
Eyi jẹ bi imọran mi fun ọ.
Wayi o: L'ori ọrọ ti nbẹ nilẹ
Ti mo fẹ sọ f'ọmọ araiye;
Mo nfẹ k'onkawe tẹti
Ki nwọn gbọ afikun ọrọ.
N'ijọ oju npọn aiye,
Aiye ke pe Ọga Ogo
Pe, ko ba wọn t'aiye ṣe.
Ajakalẹ arun nja ranin
Ọmọ eniyan ke pe Olodumare;
Iku nrọdẹdẹ l'ori ẹda,
Aiye npe Olodumare
K'o ba ni d'iku lọwọ
Ebi npa aiye,
Nwọn ko r'omi, nwọn ko r'ojo
Ọja ọwọngogo wọ ilu,
Awọn ọlọṣa npaniyan rẹpẹtẹ
Gbogbo eniyan ndaamu
Nwọn nke pe Olodumare
Ko le rọgbọ fun wọn.
Oluwa Ọba kọkọ kọ eti ikun
O ni, Oun ko ni i gbọ 'gbea raiye;
Oluwa ko fẹ gba ipẹ
Nitori ẹṣẹ ọmọ eniyan;
Awọn eniyan jarigidi sẹkun
Nwọn nke tọsantoru
Pe, k'Oluwa Ọba ko wọn yọ
Asẹhin wa asẹhin bọ,
Ọba Oluwa mi gba ipẹ.
Ọba Oluwa gba ipẹ tan
Aiye ọmọ araiye tun roju,
Ara nrọ eniyan ilu
Gbogbo wọn si n'ibalẹ aiya,
Nwọn wa n'ibalẹ aiya tan
Ayie kọ jalẹ,
Nwọn ko dupẹ mọ ! !
Nwọn wa yipada
Nwọn nf'ogo f'ewurẹ,
Nwọn yipada kia
Nwọn nf'ogo f'agutan !
Nwọn nf'ogo f'Ooṣa lasan
Nwọn nf'ogo f'Oke gogoro !
Nwọn nf'ogo fun Ṣango
Nwọn nfi f'Ooṣa Oke !
Ọtọ l'ẹni ṣe ni l'oore,
Ọtọ l'ẹni a a nf'ọpẹ fun !
Ẹṣẹ nla l'eyi jẹ
T'ọmọ araiye nda t'aa! fura
Ẹṣẹ tii fa 'jiya l'eyi
Mo fẹ ki ẹ mọ delẹdelẹ.
Ati gbogbo eyi t'Ajao ko wi
Ẹṣẹ na ni s'Oluwa Ọba
Ẹ jẹ k'a f'ọrọ yi kọgbọn
K'a yee da a ni Naijiria.


POOLS! POOLS!!

Special Gift

3 8 27


L. Hamed Tip

22

28

40


IWE IGBAẸLODE

DARA PUPỌ, RA TIRẸ NIBẸ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi, Iṣin St., Isalẹ Koto P. O' Box 17, Ilọrin



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

# Akédé ọ̀nà Iyè

ONA SI IYE AINIPEKUN

# A O Re Agberaga sile (3)

Ẹ gbọ, ki ẹ si fi eti silẹ; ẹ ma ṣe gberaga: nitori Oluwa ti sọrọ. Jeremiah 13; 15.

Ẹsẹ wura ti a tọkasi ni ibẹrẹ iwaasu yi ni iran ti Oluwa fi han Woli Jeremiah nigba ti Oluwa tọ ọ wa. Ohun ti Oluwa si ri nigbana ni iwa IGBERAGA Juda ati igberaga ti o nṣẹlẹ ni Jerusalẹmu, eyi ti o mu ki ọpọ fi Ọlọrun silẹ ti nwọn si nbọ ere oriṣa paapaa julọ, ti nwọn fi ni igbẹkẹle ninu olowo ju Ọlọrun lọ.

Nitori eyi ni Oluwa Ọlọrun Ọrun ti O ni aiye na, nibiti awọn enia na ti nhuwa igberaga ṣe tọ Woli Jeremiah lọ lati kilọ fun awọn enia na pe: "Ẹ gbọ ki ẹ si fi eti silẹ; ẹ ma ṣe gberaga: nitori Oluwa ti sọrọ".

Njẹ iru iwa igberaga na ti Oluwa titori rẹ ṣe ikilo fun awọn ara Juda ati Jerusalẹmu, kọ ha ni ọpọlọpọ enia aiye yi, paapaa ọmọ ile iwe, ọmọ ile ikọṣẹ, oṣiṣẹ, ọmọde ati agbalagba lọkunrin lobinrin titi de ile isin sọ di oun ayọ wọn l'ode oni?

Ṣugbọn ẹ jẹ ki o tun ye olukuluku enia ti nka iwaasu yi l'oni; gẹgẹ bi a ti ntẹnumọ ọn fun nyin pe: Oluwa korira iwa igberaga ni o ṣe nṣe ikilọ l'ori rẹ. Gbogbo enia aiye yi ni O si nṣe ikilọ na fun , ki iṣe fun Juda ati Jerusalẹmu nikan. Nitorina tete gbọ ikilọ na l'oni ki o si fi gbogbo iwa igberaga silẹ nitoripe, a o rẹ agberaga enia silẹ.

Awọn ọmọ aiye yi a maa tan ara wọn jẹ ninu iwa igberaga wọn nitori awọn nfẹ gbayi l'oju ọmọ enia.

Nigba ti Oluwa ba ṣe onigberaga enia l'oore, a maa ro pe ọgbọn tabi agbara oun ni oun fi ṣoriire. Kaka ki o dupẹ lọwọ Oluwa ki o si maa fi iwa irẹlẹ lo oore na, nṣe ni onigberaga yio wa maa pariwo ara rẹ kiri pe, ẹni nla ni oun iṣe.

O le ma ti i kọle ki o sọ pe oun ni ile ni Abẹokuta. O le sọ pe bi iru oun ko ba si nibi ọrọ ilu, ilu ko le dara. O le sọ pe awọn ni awọn nmu ẹsẹ ilọ duro ati bẹẹbẹẹ lọ.

Ni kukuru, ko si oore ti Oluwa yio ṣe onigberaga enia ti yio dupẹ lọwọ Oluwa nitoripe afibiṣu-oloore enia ni agberaga iṣe nitori o gba pe nipa agbara ati pe ọgbọn oun tni oun fi tobi.

Ọkan onigberaga ko le balẹ lailai nitoripe bi ko ti to ni yio maa sọ pe oun to, ohun ti

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

ko le ṣe ni yio si maa dagbale: Bi onigberaga ni nkan meji, mẹrin ni yio pe e.

Bẹẹ ni, aṣiri onigberaga ki i bo di ọjọ iku rẹ. Ọpọ ninu onigberaga l'o jẹ pe nigba ti nwọn ba ku tan ni aṣiri wọn maa ntu sita fun gbogbo enia, ohun ini wọn a si di ti ẹni ẹlẹni. Eyi l'o mu mi ranti itan kekere kan.

ITAN

"Ni akoko kan ilu kekere kan wa ti njẹ Oṣuba. Nibẹ ni a ti bi ọkunrin kan ti njẹ Tamutamu. Tamutamu ti a nwi yi jẹ ọlọyaya enia, o si maa nṣere pupọ.

Nipa bẹẹ, awọn obinrin fẹran rẹ pupọ. Ki i wọṣọ olowo pọọkupọọku bikoṣe olowo gege, o si jẹ agbẹ.

O ṣe ni ọdun kan, gbogbo ohun ọgbin oko Tamutamu ni iṣu agbado ati bẹẹbẹẹ lọ bẹrẹ si i dara tobẹẹ ti nwọn fi fun un ni iyawo. Bayi ni Tamutamu di oniyawo.

Ṣugbọn iyawo kekere yi ko tẹ ẹ l'ọrun, o si lọ gba iyawo baba kan ti nwọn npe ni Orebe. Ko pẹ pupọ ti o gba iyawo yi ni ohun ini rẹ bẹrẹ si i lọ sẹhin, o wa bẹrẹ si i ya owo kiri.

Gbogbo owo ti Tamutamu nya ile alawo ni o tun nko o lọ pe ki nwọn ṣe oogun fun oun ki "ọwọ aiye" ma ṣe ka oun.

Bayi ni Tamutamu di onigbese ti awọn olowo si nfa a kiri. Nigba ti ko wọ mọ, Tamutamu sakuro ni ilu lọ si ilu kan ti o to ọgọrun ibusọ si Oṣuba. Ilu na njẹ Oloo.

Ilu Oloo yi ni Tamutamu de ti o bẹrẹ si i parọ jẹun. Eyi ni o nba kaakiri ti o fi lọ wọnu ẹgbẹ buburu kan ti nwọn npe ni Ayidalẹ. Ẹgbẹ ti a wi yi l'o ya a lowo ti o fi ra burọṣi (brush ati irin iṣẹ ile kikun ti o si sọ ara rẹ di kunlekunle

Bayi ni Tamutamu bẹrẹ si i gberaga kaakiri pe, "ilu nla" ni oun ti wa ati pe, oun kọ ile kan si ilu oun ti o jẹ aja mẹta.

Ṣugbọn ṣaaju, awọn iyawo meji ti Tamutamu kokuro nile wa si idalẹ sapada si ilu wọn, nibi ti nwọn ti fẹ ẹlomiran toripe, kaka ki ewe agbọn dẹ ni ọrọ Tamutamu da ni ilu Oloo, nṣe ni o tun nlekoko sii.

Igberaga ti ba Tamutamu l'aiye jẹ, iṣẹ kunlekunle ti o nṣe ko pe e. Ko le da owo ẹgbẹ ti o ya pada ko si le dawo sinu ẹgbẹ.

Iwe ibanujẹ ti nwọn nkọ si Tamutamu lati ile tun wa mu ironu ba a. O ri iwe gba pe, ọkan ninu awọn enia ti o jẹ ni gbese nile ti fi ile baba rẹ kan ti o jẹ ojule mẹrin di gbese ti o jẹ ẹ, awọn mejọ miran ti o tun jẹ ni gbese si nreti rẹ ki o wale ki nwọn le pe e l'ẹjọ gbese ti o jẹ wọn.

Ironu wa da ori Tamutamu kodo, ọjọ kẹrin ti o ri iwe na gba ni Tamutamu jabọ l'ori ile ti o nba ẹnikan kun lọwọ; o fi ori sọlẹ, o si ku bamubamu !

Laifa ọrọ gun, nwọn ta gbogbo ohun ini rẹ, nwọn fi gbe oku rẹ lọ si ilu rẹ. Nigba ti nwọn ba Tamutamu de ilu rẹ ni gbogbo enia wa mọ pe, Tamutamu ko tilẹ kọ aba (ati-baba) de ibi ti yio kọ ile alajamẹta.

Ọrọ Tamutamu wa di apero. Ko kọle ti nwọn le sinku rẹ si, ẹni ti o jẹ lowo si ti gba ile baba rẹ di gbese, nibo ni awọn enia yi yio wa sinku Tamutamu si ?

Nigba ti nwọn ri i pe, oku Tamutamu jẹ oku wahala, nwọn pinnu, nwọn si dana sun un. Bayi ni nwọn dana sun Tamutamu lati aiye lọ toripe oku rẹ da ija silẹ laarin ilu nipa gbese ti o jẹ."

Itan na l'o ti gbọ yi, iwọ ọmọ enia: Ẹkọ wo ni o fẹ kọ ninu igbesi aiye Tamutamu? A ha le sọ pe iru igbesi aiye ti Tamutamu gbe yi dara bi?

Bi ko ba dara, ki l'o fa a ti aiye Tamutamu fi pari bẹẹ? Ohun ti o fa a ni iwa igberaga. Ani, iwa igberaga ti Oluwa nṣe ikilọ rẹ fun iwọ ati emi pe; "Ẹ gbọ ki ẹ si fetisilẹ; ẹ ma ṣe gberaga nitori Oluwa ti sọrọ" Jeremiah 13;15.

Oluwa ti kilọ ṣugbọn Tamutamu ko gbọ, a si rẹ ẹ silẹ ninu igberaga rẹ.

Bi igberaga ba bale enia, irọ ni yio maa pa kiri. Bi okoto irọ rẹ ba si fọ l'aiye, oun na ni yio ru itiju rẹ nitoripe, bi aṣiri irọ onigberaga tilẹ bo nigba ti o ba wa l'aaye ọjọ iku rẹ ni aṣiri rẹ yio tu nitori

(Woju Ewe Kẹfa)

NIGERIA NEW STATES CO.

NNSC

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.

# Ẹ gbọ t'ẹmi

## É gba wa lowo omi oniyo

OLOOTU,

GBA mi l'aye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Eko lati jọwọ ko awa ti a wa nilu Eko yọ ninu omi oniyọ ti a nmu ni ilu na nitoripe omi na ko dara fun alaafia ara rara. O nya enia ni igbẹ, ko si ṣe e mu ni amugbadun.

Awọn agba a si maa powe pe, "Agba ki i wa l'ọja ki ori ọmọ titun wọ", Nitorina, ki Ijọba ba wa mojuto ọrọ na ki omi oniyọ ma wa da idakuda silẹ ninu ilu.

Emi ni,
Saidu Ọlalekan Afọlayan,
Eko

## Mo si fila fun Atioro

OLOOTU,

MO kan saara gidi si Ọlọla Atioro, Ọmọ Atiala l'ori Nasia rẹ "Oore t'o dara" ti o nṣe lọ yi nitoripe ọrọ gidi ni Nasia na jẹ.

Mo fi pẹlẹpẹlẹ ka a, o si ye mi yekeyeke. O ṣẹṣẹ wa ye mi ni pe, ọpọlọpọ oore ni enia maanṣe ti ko dara, ti ko l'abọ, ti o tun le fa ibinu Ọlọrun ba ni.

Mo ti fi Nasia na kọgbọn pupọ, mo si rọ ẹnyin onkawe lati tun un ka ki ẹ si fi oye gbe e, bọya asọdun ni mo nsọ.

Mo ṣifila fun Atioro ọmọ Atiala, baba Atiẹlẹ. Ọpọlọ rẹ ko ni i daru o.

Eni ni,
Timmy Iṣọla,
Eko

## Oro fun Omo Ilero

OLOOTU,

JỌWỌ gba mi l'aye lati sọ gbolohun ọrọ meji kan fun awọn ọmọ ilu mi ni Ilero.

Ohun ti mo fẹ ba wọn sọ ni pe, ki nwọn gbiyanju lati pari eto meji pataki ti nbẹ niwaju wọn kiakia. Ekinni ni Mọṣalaṣi nla ti ilu na ati Muslim High School ti nwọn fẹ ṣe si ilu na.

Eto mejeeji yi ni awọn ara ilu ti ndawo fun lati ọjọ pipẹ wa, o si yẹ ki awọn ti o wa nidi ọrọ na tilẹ bẹrẹ iṣẹ l'ori eto mejeeji ki ori ba le ya awọn ara ilu lati le tun maa nipa ninu didawo idagbasoke ilu na.

O ti to ọdun mẹsan bayi ti nwọn ti dawọle kikọ Mọṣalaṣi nla ti ilu na ṣugbọn ti nwọn ko kọ ọ pari.

A fẹ ki awọn ti ọrọ mejeeji yi ba kan ki awọn tete bẹrẹ iṣẹ l'ori wọn kiakia.

Emi ni,
Rasaki Katibi,
Ilero–Ọyọ

## Aanu ara Eko se mi

OLOOTU,

ODODO ni owe ti awọn baba wa npa pe "Nibi ti aaka ti nsunkun pe oun ko ni ehin, ni ajanaku ti nsunkun pe oun ko ri ete fi bo ti oun."

Nibi ti awọn enia ilu nlanla yoku ni ilẹ Naijiria ti nmumi amugbadun ni awọn ara Eko ti nfi girimakai fi iyọ ṣe omi mu.

Aanu awọn olugbe ilu na ṣe mi pupọ nitoripe omi ṣe pataki pupọ ninu igbesi aiye ọmọ enia. Adura mi ni pe, Ọlọrun yio ṣọjo aanu silẹ fun nyin o, Aamin.

Emi ni,
Oseeni Kọlapọ,
Ibadan.

FOR ALL YOUR

Electronics

Fans, Cookers, Radio sets, T.V.& Colour T.V. sets, coolers etc: at resonable prices

PATRONIZE

Aiyedetisola

Commercial

Electrical

Store:

N27 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

# O l'ewu lati maa s'orikunkun — Lajide

NWỌN ti fun awọn awakọ takiṣi nilu Ogbomọṣọ n'imọran lati maa din are sisa ku ni igboro nitori aabo ẹmi wọn ati ti awọn miran pẹlu.

Bakanna ni nwọn tun gba wọn n'imọran lati yẹra fun nkan mimu yala ọti tabi nkan miran eyi ti o le gbun wọn ni kẹsẹ tabi mu wọn huwa yatọ si bi o ti yẹ gẹgẹbi ọmọluabi nigbati nwọn ba nwakọ lọ l'opopo ọna.

Alaga ijọba ibilẹ ilu Ogbomọṣọ, Oloye Victor Ladipọ Lajide l'o parọwa yi fun awọn awakọ takiṣi nigbati o nba Alaga ati awọn aṣoju ẹgbẹ awọn awakọ na sọrọ nile iṣẹ rẹ lai pẹ yi.

Oloye Lajide ko dunnu sibi pupọ l'ara awọn awakọ gbogbo ṣe maa nhuwa loju ọna nigbati nwọn ba nwakọ, bẹẹ si ni ijọba ko yee polongo lojojumọ pe ki nwọn rọra maa sare nigbakugba. Nitorina, o rọ wọn lati fi opin si iru iwa bẹẹ nitori gẹgẹ bi o ti wi, "Ewu gbaa ni lati maa se orikunkun".

Nigba ti o nfesi loruko awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ, Alaga awọn awakọ takiṣi fun ilu Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ, Ọgbẹni Tunde Ogunniran, dupẹ gidigidi lọwọ Oloye Lajide fun awọn akiyesi ati imọran rẹ gbogbo.

Ọgbẹni Ogunniran ṣe oriṣi alaye lati pon lẹhin awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ pe awọn ko fi igba kankan ṣe orikunkun si aṣẹ ijọba tabi si aw n alaṣẹ.

Ṣugbọn ṣa o, Ọgbẹni Ogunniran jẹjẹ pe awọn yio wo nkan ṣe si ọrọ na ṣugbọn Ọgbẹni Oguniran ko fi ara mọ ẹsun ọti mimu tabi nkan miran ti i se ni ṣibaṣibo pe, iru eyi ki i ṣẹlẹ nigbati awon omo ẹgbẹ oun ba nwakọ. O tẹnu mọ pe, ko si otito kan ninu ẹsun na.



OLOYE VICTOR LAJIDE
Alaga Kansul Ogbomọṣọ.

## Islaudeen Akeukawe fe ko Koleji

IROHIN ti o tẹ wa lọwọ lati ilu Iwo fi ye wa pe, ọpọ enia ni o wa sibi ayẹyẹ ikowojọ ti ijọ Islaudeen Akewukawe ṣe laipẹ yi si ilu na lati kowojọ fun kikọ Mọṣalaṣi Jimọ ati ile iwe giga kan si ilu na.

Alaga eto ayẹyẹ na ni onisowo kan ni ilẹ Naijiria, Ọgbẹni Biọla Ogundokun, ẹni ti o fi ẹgbẹrun Naira (₦1,000.00) ran Ijọ na lọwọ.

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Ogundokun sọ pe, inu oun dun pe a ri ẹgbẹ Musulumi kan ti o ronu lati da ile iwe Girama silẹ nilu Iwo nitoripe gbogbo enia ni o ti mọ ilu Iwo gẹgẹ bi ilu Alaafaa.

Siwaju si i, Ọgbẹni Ogundokun sọ pe, ẹsin lai si imọ iwe ko le nilọsiwaju, o si rọ olukuluku enia ilu na lati ni ifẹ si ẹkọ iwe pẹlu.

Bakanna ni awọn enia miran ba wọn sọrọ iwuri l'ọjọ na, nwọn si rọ awọn ara Iwo

(Wo Oju Ewe Keje)

## Owoeye

(Lati Oju Ewe Kẹrin)

nwọn yio pitan bi o ti lo aiye rẹ ati ohun ganan ti o jẹ ninu aiye, le oku rẹ l'ori; awọn enia yio si maa sọ gbogbo aleebu rẹ nigba ti oun ba ti kọja lọ sinu iho.

Nitorina iwọ ti a fun ni oore-ọfẹ lati ka iwaasu yi l'oni, iwọ ki yio ha ronu ki o si fi gbogbo iwa igberaga silẹ nitori Oluwa ko fẹ ẹ. Ranti pe, ọjọ kan nbọ ti a o rẹ iwo giga enia silẹ, a o si tẹ ori agberaga enia ba, Oluwa nikanṣoṣo li a o gbega li ọjọ na: Isaiah 2;11.

ADURA

Oluwa, ma ṣe jẹ ki ẹmi igberaga ti Iwọ ko fi ni i gb'ohun mi wọ inu mi. Ti o ba si ti wa ninu mi, ba mi yọ ọ jade; nitori Jesu Kristi Ọmọ Rẹ Oluwa wa, Aamin.


**IWE ỌRỌ ỌLỌRUN**

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.


## Ayangunna komo jade

IROHIN ti o tẹ wa lọwọ lati ilu Jos ni Oke-Ọya fi ye wa pe, laipẹ yi ni Ọgbẹni S. A. Ayangunna ṣe ikojade omokunrin kan ti Oluwa fi ta oun ati aya rẹ l'orẹ.

Ẹni-owo Pastor Akande l'o ṣeto isomo-loruko na ni ilana awon Onigbagbo, oruko ti nwon si so omo na ni: Matthew Olu Ayantunnbi, iya ati baba omo na si fi jijẹ-mimu tẹ tẹgbẹtogba t'o wa sibẹ l'orun.

Ẹgbẹ Independa wa, Ẹgbẹ Ọrẹdẹgbẹ wa, Ẹgbẹ Alatunṣe si wa sibẹ pẹlu.

Ara awon enia ti o wa sibẹ ni: D. A. Ọyateru, S. A. Adeṣina, E.O. Babalola, C. A. Akanbi, Akinade Ladapo, Aderinto, Adelẹyẹ, Sam Odulẹyẹ E. F. D. Alade Joseph Adeboye, Moses Ayangunna, Ester Adeoye, Esther Ibilola Akanbi, D. A. Faṣola, J. A Lafa ati Labi Ayanlere.

## Sirajudeen se bebe

AṢAAJU Ẹgbẹ Musulumi kan ti njẹ Sirajudeen Society, Alhaji O. A. Ibiyẹmi sọ pe, l'ẹnu iwọn ọdun marun ti Ẹgbẹ na daiye, o ti da ile iwe alakọbẹrẹ rẹpẹtẹ silẹ kaakiri, bẹẹ ni ile iwosan ti o nko si Iba lẹba Ikirun yio pari titi ọdun yi.

Nibi ifilọlẹ ẹka Ẹgbẹ na ti o waiye nilu Eekọọsin ni agbegbe Oṣun l'o ti sọrọ na.

Alhaji Azeez Ajagbemọkeferi ti o jẹ gbajumọ Oniwaasi kan wa nibẹ pẹlu, o si rọ olukuluku Musulumi lati maa nipa ninu ohunkohun ti o ba le mu agbega ba ẹsin Islam.


## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyokan, ₦2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

(1) Alufaa Igbaẹlode
N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin




# Awon Oniwaka Obinrin meji

L'ONI awo awọn alare waka meji ni a o fi irohin wọn to yin leti. Obinrin ni awọn alare mejeeji na; bẹẹ ni awọn olufẹ are waka ti bẹrẹ sii du awon awo wọn na ra bi akara gbigbona.

Ile-Iṣẹ ỌMỌ AJE SOUND STUDIO ti nwọn jẹ olokiki ninu iṣẹ titẹ rẹkọọdu asiko jade ni o ṣiṣẹ l'ori awo na, ile-itaja atarẹkọọdu nni ti o gbajumọ bi iṣana ẹlẹẹta ALETUNJI STORES ni Olupinja awo na fun gbogbo onişowo atarẹkọọdu jakejado Orilẹ-ede yi, ki o ba le to gbogbo olufẹ are waka na lọwọ nibikibi ti nwọn le wa ni Orilẹ-ede Naijiria.

Awo akọkọ ni ti Sikiratu Ayan ati ẹgbẹ alare waka re, eyi ti Nọnba awo rẹ jẹ OLPS 0109.

Sikiratu Ayan kọ orin ti o mu ọgbọn dani, bẹẹ ni orin na dun pupọ.

Ninu rẹkọọdu rẹ yi, lẹhin ti o juba, adura pataki l'o ṣe fun gbogbo enia; bakanna ni o tun ṣe adura fun awọn alaboyun, ki o to bẹrẹ si i kọ orin agbọdunnu ti oun ati elegbe rẹ si bẹrẹ si i fi orin dapara si ara wọn.

Onilu rẹ na ko kẹrẹ pẹlu ilu a gbọ f'ẹsẹ rajo eyi ti o jẹ ki awo na tun dara fun faaji tabi lọjọ nkan ẹyẹ. O tilẹ tun dara ki awọn ọkọlobinrin ti iyawo wọn ịoyun sinu ati awọn t'o wa lọwọ "A nbẹ 'Luwa" ki nwọn ni awo na sile fun amunudun ati fun adura.

AWO KEJI

Awo Keji ni ti gbajumọ alare waka Obinrin bi Ọkunrin nni, Alenọtu Ramọnu ati awọn alare waka rẹ, ẹni ti o dan nkan wo ninu awo rẹ yi.

Nọnba awo na ni OLPS 0111.

Ninu awo rẹ yi, o fi Ipinlẹ titun kọrin, paapaa, Ipinlẹ Ogun.

Lẹhin ti o dupẹ lọwọ Ijọba Ologun Apapọ fun iṣẹ nlanla ti nwọn ṣe o wa kesi Ijọba Ipinlẹ Ogun lati maṣe gbagbe Ijẹbu Eti-Odo fun awọn nkan amuludun eyi ti o njẹ awọn ilu na niya.

O ni ko si ina, ko si titi, nitorina, ki wọn ba awọn ṣe titi, ki awọn le ribi maa mu ounjẹ jade nitori ounjẹ ni ọrẹ awọ.

Eyi nikan kọ ni o fi kọrin. O tun fi wundia ati Adelebọ kọrin. Bakanna ni o tun. Iki awọn ẹgbẹ Ifẹlodun ati bẹẹbẹẹ lọ.

Ni gasikiya, o ṣe are aladun manigbagbẹ sinu awo rẹ yi.

Awọn rẹkọọdu mejeji yi ti o jẹ pe awọn gbajumọ alare Obinrin ni nwọn ṣe e pabanbari o si tubọ jẹ ki awọn na gbe igba eroke eyi ti o fẹ fi han pe "Ko si nkan ti Ọkunrin nṣe ti Obinrin ko le ṣe"? nitoripe are wọn kuro ni wẹrẹwẹrẹ.

Gbogbo ile itaja rẹkọọdu jakejado ilẹ Naijiria ni ẹ ti le ri awo wọnyi ra, tabi taara l'ọdọ Adetunji Stores,
2, Ibomọ Street,
Agarawu, Lagos.
* Sw6/431 Old Armel's Road, Ogunpa IB.
*Sw3/51 Adetunji House Popoyemọja, Ibadan.

## ALENATU RAMONU
ATI AWON ALARE WAKA RE

# Titiloye di ero orun

NWỌN ti kede iku gbajumo onişowo kan nilu Eko, Alagba Clement Ọladiipo Titiloye Aro ti iṣe baba Ẹgbẹ Ijo Saint Joseph Catholic Church nilu Eko. Ọdun marundinlogorin ni o lo ni aiye.

Gẹgẹ bi irohin ti wi, ni ojo Satide ti iṣe ojo kẹrindinlogun oṣu kẹrin odun yi ni o jalaisi.

Ni oni Satide ti iṣe ogbonjo oṣu kẹrin odun yi ni nwon yio sinku rẹ ni ilu rẹ Oro ni Ipinlẹ Kwara ni deedee agogo mẹrin irolẹ ni ile isin Ijo Aguda ti njẹ St. Andrews Catholic Church, Oro.

Irohin fi ye wa pe, opolopo enia lati idalẹ paapaa ilu Eko ni yio pejupesẹ sibi isinku na.

Ọpo omo ati omoomo l'o gbẹhin Oloogbe na. Ara won ni: Michael Ọlayode Titiloye, Ọlatẹju Titiloye Joseh Tokunbo Titiloye Peter Ọlabisi Titiloye ati Ọlanikẹ Titiloye.

## Ebi ranti Alhaji Lawal

NI ọjọ kẹtadinlogun oṣu kẹrin ọdun yi ni awọn ara, ọrẹ ọmọ, ẹbi ati iyekan oloogbe, Alhaji Buraimọ A. Lawal ẹni ti o ṣe alaisi ni ọdun ti o kọja, ṣe ayẹyẹ akanṣe eto adura l'ona ẹsin Muslim gẹgẹbi ọkan l'aja eto fun iranti rẹ ni adugbo Iṣapa, nilu Ogbomọṣọ ni eyi ti waiye.

Alhaji Amọdu Alao, ti iṣe Mọgaji Iṣapa, Ogbomọṣọ l'o ṣaaju eto akanṣe adura na. Ọpọlọpọ Alhaji ati Alhaja pẹlu agbagba ẹlẹsin Muslim lo peju sibi adura na.

Lẹhin akanṣe adura na ni wọn ṣe inawo fun gbogbo awọn enia ti o wa lati ba wọn ṣe iranti Baba ati iyekan wọn na, awọn ẹbi oloogbe na si na wo pupọ l'ọjọ na.



ALHAJI LAWAL

Die ti aye wa fun lati darukọ l'ara awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni. Ahaji Rufai Dapọ ti ise Lemọmu Sarumi, Alhaji Baṣiru Ile Onilu Alfa Yuṣuf Ayinla, Alfa B.A. Balogun, B. A. Amọdu ati bẹẹbẹẹ lo.

Ni ojo kanna ni meji l'ara awọn ọmọloku na kọṣẹ yori. Awọn ọmọ na ni: Kasali Lawal ẹni ti o ko iṣẹ atunmọtoṣe (Mechanic) ati Isamọtu Lawal ẹni ti iṣe jorinjorin (welder).

Bakanna ẹwẹ ni awọn ẹbi si fi jijẹ tẹ awọn alabaṣẹyẹ l'ọrun ni ọjọ na.

## Islaudeen

(Lati Oju Ewe Kẹfa)-lati yago pẹlu ohun ti o ba korira ẹkọ iwe nitoripe, eyi ko le ran ẹsin Islam lọwọ.

Ara awọn enia ti o sọrọ nibẹ ni Dokita L. K.Windokun, Alhaji R. O. Aliyu Ọgbeni Tunde Bọlarinwa, Alhaji Lateef Adekilekun, Alhaji M. Badrudeen,

Bakanna ni Oluwo Iwo, Ọba S. O. Abimbọla fi Ọgọrun Naira ran Ijọ na lọwọ, o si ṣeleri ninu iṣẹ ti o ran si wọn pe, bi iṣẹ na ba bẹrẹ, oun yio maa fun wọn logoji apo sibẹnti loṣooṣu titi iṣẹ na yio fi pari. Ẹgbẹtalelogun (₦4,600.00) ni nwọn kojọ l'ọjọ na.

## Babalola jade l'aiye

(Lati Oju Ewe Keji)

ni Iyaafin Sikiratu Akinola, Alhaji Fatai Adio, Oyerogba, Ọgbẹni Lateef Bolaji Oloke, Lateef Babalola.

Bakanna ni awon omo Alapinni nilu Eko ati Ọyo l'abẹ aṣiwaju won Oloye Bolarinwa Alapinni Ọyo ati ati awon aburo oku, Ọgbẹni M. Lijadu ati Ganiyu Akin tunde nawo nara fun awon enia ojo na.

Ọgbẹni O. Kolawole Ọladẹjo Ṣiba ti o jẹ gbajumo Akewi, ni o fi ewi Igbalode ti o kọ nipa oloogbe Babalola da awon enia ojo na laraya.

# Okunrin kan be olopa lori

(Lati Oju Ewe Kinni) muyẹ na lọ ṣe iwadi si.

Gẹgẹ bi irohin na ti wi, awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ mẹta labẹ ọga kan, Ọgbẹni ASP S. M. Pedro, ni o lọ fun iwadi na. Kọburu meji ti o tẹle e ni C. Mbadiugba ati Tunde Maclean, Nicholas Ike ni o si wa wọn lọ sibẹ.

Alaye ti ile iṣẹ Ọlọpa ilu Abakaliki ṣe l'ori ọro na sọ pe, nigbati awọn Ọtẹlẹmuyẹ na de abule Izzi ti nwọn si nwadi ọrọ l'ọwọ l'ọdọ awọn enia ni ọkunrin kan dede yọ si wọn pẹlu ada kan ti o nkọ yanranyanran lọwọ rẹ, ti o si bẹrẹ si i ṣa awọn Ọlọpa mẹrẹẹrin ni iṣakuṣa.

Irohin sọ pe nigbati ọkunrin na ri i pe ẹnikẹni ninu awọn Ọlọpa na ko le mira mọ, ni o ba poora sinu igbo.

A gbọ pe nihin ni okiki ti kan ti awọn Ọlọpa si ti ilu Abakaliki wa sibẹ. Nigba ti nwọn debẹ, nwọn ri i pe Ọlọpa ti o wa mọto ti ku, awọn Ọtẹlẹmuyẹ mẹta yoku si njowere ninu agbara ẹjẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa gbe oku Dẹrẹba tihin lọ sile iwosan ilu Abakaliki fun ayẹwo, awọn Ọlọpa mẹta ti njowere iku si wa nile iwosan na ni ẹsẹ kan aiye, ẹsẹ kan ọrun.

Irohin miran lati ilu Abakaliki sọ pe bayi, abule Izzi ti di ahoro, bẹẹ ni awọn Ọlọpa ti o diihamọra ogun ti bẹrẹ si i wa tigbotiju agbegbe na ka lati ri ọkunrin apania na mu.

Irohin fi kun un pe bayi ni agbegbe na, olukuluku enia l'o nsan ọbẹ lalu ti nwọn si nfi ada kọ iha kaakiri igboro lai tẹle aṣẹ ti awọn Ọlọpa ti pa ṣaaju nibẹ pe, ẹnikẹni ko gbọdọ mu ada lọwọ ni igboro.

IJOYE ILU NI!

Irohin ti o ṣẹṣẹ tẹ wa lọwọ lati Abakaliki fi ye wa pe Ijoye kan ni ilu Izzi ti lọ fi ara rẹ han awọn Ọlọpa nile iṣẹ wọn nilu Abakaliki pe, awọn ọlọṣa wa sile oun, oun ṣe wọn bi ọṣẹ ti i ṣoju, oun si pa ọkan ninu wọn nigba ti oun nile wọn lọ.

Irohin sọ pe, nigba ti Oloye na sọ bayi, Ọgbẹni Charles Machie ti iṣe Ọga Ọlọpa ti o ba nibi iṣẹ ko jẹ ki Ijoye na pada sile mọ.

A gbọ pe, ile Ijoye yi gan-an ni awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ ti lọ nfi imu finlẹ l'ori ẹsun ipania kan ti nwọn sọ pe o ṣẹlẹ ni oṣu keji ọdun yi, eyi ti a gbọ pe o kan Ijoye na gbọngbọn.

Ijoye na ti o lọ fi ara rẹ han Ọlọpa yi ni o fi awọn Ọtẹlẹmuyẹ na pe "ọlọṣa" ti o wa ka oun mọle, ti o si da ada bo wọn.

## Oyerinde

(Lati Oju Ewe Kinni)

ogboju opitan ati ẹni ti o kọ iwe itan ilu Ogbomọṣọ, oun si ni Ọtun Ṣọhun Ogbomọṣọ titi ọjọ iku rẹ.

Ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu karun ọdun yi ni nwọn yio sinku rẹ.

## O SE ALAISI

A kede iku Baba wa ọwọn:

ALAGBA JOHN AYANDELE ti iṣe Ako, Oṣupa, Ogbomọṣọ, ẹni ti o sun ninu Oluwa ni ọjọ 'Bọ ti iṣe 14/4/77. Ẹni ọdun mọkanlelaadorun ni iṣe.

Ọpọlọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ l'o gbẹhin rẹ. Ara wọn ni: Ọgbẹni V. A. Ayandele, African Alliance Insurance Co; Ogbomọṣọ, Professor B. A. Ayandele, Vice-Chancellor, University of Calabar ati Tayọ Ayandele, NTC, Ibadan.

A o maa kede eto isinku nigba ti o ba ya.

V. A. AYANDELE
(Fun Gbogbo Ẹbi).


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI TUN GBE ORIRE DE.
A TI GBE TANA DANU
A TUN GBE OMIRAN DE
A TI NI ẸRỌ ATATA YI:



## Cassava Grater

(WITH JLO L101 ENGINE) **(N350.00)**

(EYI NI ẸRỌ TI NWỌN FI NRIN GARI OLOWONYỌ

Aiye ti di jẹlẹnkẹ,
Ko si ki a maa fi agbara wa owo mọ
Bi o ba ti ni ẹrọ yi kanṣoṣo
Jẹ ki ọkan rẹ balẹ pẹsẹ
Nitoripe owo-nlanla
Ni lwọ yio maa pa.
Owo ẹrọ na ko pọ rara
₦350.00 pere ni.
Ẹ maa bọ taara si:

**Western Nigerian Technical Company Limited**

WENTEC 1955

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/496B Yemetu Aladorin P. M. B. 5230, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, E4/803, Aperin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27817.